

# Tani Mi Ti ỌBA Kan Yio Fi Ku Nipo Mi?

Akojopọ Lati Ọwọ Watson Goodman

Ọfe — Ki Ise Fun Tita

# TANI MI

Ẹlẹda wa mọ ẹniti awa ise, O si ti fi gbogbo rẹ han kedere ninu ỌRỌ aiyeraiye Rẹ nibiti a ti le ri "iru Ẹniti A Da Wa", "ohun ti a da", "Ibiti Eyi Ngbe wa re", ati "ohun ti a tun le da" nipa gbigba igbasilẹ Ọlọrun.

Ọpọ ni ko mọ nipa igbasilẹ Ọlọrun. Ọpọ mọ apakan nipa rẹ nwọn si nilo lati wadi kinikini sinu rẹ. Ọpọ ni o kọ oju ija si igbasilẹ Ọlọrun yi, nigbati awọn miran nfi tifẹtifẹ rọ mọ, ati pe bi a ti nda wọn silẹ wọn ri pe awọn ti di ẹniti o ni opin aiyeraiye ti o ga.

Ọkan aiku mi to ohun ti mo ba jẹ ki Ẹlẹda funra Rẹ fi i se! Eyi jẹ yala kikọ Rẹ ati iyọrisi asan ninu aiyeraiye ti ko lopin, tabi gbigba Rẹ ati igbọran tootọ nipa ki a jẹ ki O mu wa pin, gẹgẹbi iyawo Rẹ, Itẹ aiyeraiye ti ise ti gbogbo aiye pẹlu Rẹ!

—Watson Goodman (1920-2002)

Oun yio ni iyawo aiyeraiye

**Isaiah 62:5**

. . .ati bi ọkọ iyawo ti iyọ̀ si iyawo, bẽni Ọlọrun rẹ yio yọ̀ si ọ.

**Matteu 25:1, 6 ati 10**

Nigbana li a o fi ijọba ọrun wé awọn wundia mẹwa, ti o mu fitila wọn, ti nwọn si jade lọ ipade ọkọ iyawo. . . . Ṣugbọn lãrin ọganjọ, igbe ta soke, wipe, Wo o, ọkọ iyawo mbọ̀; ẹ jade lọ ipade rẹ̀. . . . awọn ti o si mura tan bá a wọle lọ si ibi iyawo: a si tì ilẹkun.

Kristi — Ọkọ Iyawo

**Johannu 3:29**

Ẹniti o ba ni iyawo ni ọkọ iyawo; ṣugbọn ọrẹ ọkọ iyawo ti o duro ti o si ngbohùn rẹ̀, o nyọ̀ gidigidi nitori ohùn ọkọ iyawo. . .

**II Korinti 11:2**

Nitoripe emi njowú lori nyin niti owú ẹni iwa-bi-Ọlọrun: nitoriti mo ti fi nyin fun ọkọ kan, ki emi ki o le mu nyin wá bi wundia ti o mọ́ sọdọ Kristi.

**Matteu 9:15**

Jesu si wi fun wọn pe, Awọn ọmọ ile iyawo ha le gbàwẹ, nigbati ọkọ iyawo mbẹ lọdọ wọn? ṣugbọn ọjọ mbọ̀ nigbati a o gbà ọkọ iyawo lọwọ wọn nigbana ni nwọn ó gbàwẹ.

# 2 IDI NIYI TI ỌLỌRUN FI DA ENIYAN NI AWORAN ARA RẸ

Ko si ẹda miran ti ko niye lori to eniyan ti o to fun iyawo Rẹ

**Genesisi 1:27**

**Bẽli Ọlọrun dá enia li aworan rè, li aworan Ọlọrun li o dá a; ati akọ ati abo li o dá wọn.**

**Efesu 1:4**

**Ani gẹgẹ bi o ti yàn wa ninu rè ṣaju ipilẹṣẹ aiye, ki awa ki o le je mimọ́ ati alailabùku niwaju rè ninu ifẹ.**

Lẹtọ Lati Se Alabapin pẹlu Ọlọrun

**. . .pe nipa iwọnyi ni ki ẹnyin ki o le di alabapin ninu iwa Ọlọrun. . . — II Peteru 1:4 . . . ati alabapin ninu ogo ti a o fihàn. — I Peteru 5:1 Pe, awọn ti ki iṣe Ju jẹ alabajogun ati ẹya-ara kanna. . . — Efesu 3:6 . . .eniti o mu wa yẹ lati jẹ alabapin ninu ogún awọn enia mimọ́ ninu imọlẹ. — Kolosse 1:12 . . .ṣugbọn ki nwọn tubọ mã sin won, nitori awọn ti iṣe alabapin iṣẹ rere won jẹ onigbagbó ati olufẹ. . . — I Timoteu 6:2 Nitori awa di alabapín pẹlu Kristi. . . — Heberu 3:14 . . .ti nwọn si ti di alabapin Ẹmi Mimọ́. — Heberu 6:4 . . .ṣubgọn on fun ère wa, ki o le ṣe alabapin ìwa mimọ́ rè. — Heberu 12:10**

**Genesisi 9:6**

**. . .nitoripe li aworan Ọlọrun li o dá enia.**

**Iṣe 17:24-29**

**Ọlọrun na ti o da aiye ati ohun gbogbo ti mbẹ ninu rẹ. . . on li o fi ìye ati ẽmi ati ohun gbogbo fun gbogbo enia, O si ti fi èjẹ kanna da gbogbo orilẹ-ede lati tèdo si oju agbaiye. . . Ki nwọn ki o le mã wá Oluwa, bọya bi ọkàn wọn ba le fà si i, ti wọn si ri i, bi o tilẹ ṣe pe kó jina si olukuluku wa: Nitori ninu rẹ li awa gbé wà li ãye, ti awa nrìn kiri, ti a si li ẹmí wa; bi awọn kan ninu awọn olorin ẹnyin tikaranyin ti wipe, Awa pẹlu si jẹ ọmọ rẹ. Njẹ bi awa ba ṣe ọmọ Ọlọrun, kò yẹ fun wa ki a rò pe Ọlọrun dabi wura, tabi fadaka, tabi okuta, ti a fi ọgbọn ati imọ enia ṣe li ọnà.**

Adamu, Ti A Da ni Aworan Ọlọrun nilati Ni Itansan Ogo Gẹgẹbi Ogo Ti Ọlọrun

**I Ọba 8:11**

**Awọn alufa kò si le duro ṣiṣe nitori awọsanma na: nitori ogo Oluwa kún ile Oluwa.**

**Matteu 17:1, 2**

**Lẹhin. . . Ara rẹ si yipada niwaju wọn; oju rẹ si nràn bi õrùn; aṣọ rẹ si fùn, o dabi imọlẹ.**

# 4 LATI INU IWA MIMỌ SINU ẸSẸ ATI OKUNKUN

A Daa Gẹgẹbi Ọlọrun, Ẹniti o jẹ Mimọ

**I Peteru 1:16**

**Nitori a ti kọ ọ pe, Ẹ jẹ mimọ́; nitoriti emi jẹ mimọ́.**

Aigbọran Fa Iyapa

**Romu 5:19**

**Nitori gẹgẹ bi nipa aigbọran enia kan, enia pupọ di ẹlẹṣẹ, bẽ ni nipa igbọran ẹnikan, a o sọ enia pupọ di olododo.**

**Romu 3:23**

**Gbogbo enia li o sá ti ṣè, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun.**

Nisisiyi O Di Ẹlẹtan Ati Ẹni Buburu

**Jeremiah 17:9**

**Ọkàn enia kún fun ètan jù ohun gbogbo lọ, o si buru jayi! tani o le mọ̀ ọ?**

**Genesisi 6:5**

**Ọlọrun si ri pe ìwa buburu enia di pipọ̀ li aiye, ati pe gbogbo ìro ọkán rẹ̀ kìki ibi ni lojojumọ.**

Ọlọrun Kọ Ẹni Buburu

**Luku 13:27**

**. . .Emi wi fun nyin, emi kò mọ̀ nyin nibiti ẹnyin gbé ti wá; ẹ lọ kuro lọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ.**

Eniyan sọnu sinu okunkun

**Johannu 3:19**

**Eyi ni idajọ na pe, imọle wá si aiye, awọn enia si fẹ òkunkun jù imọlẹ lọ, nitoriti iṣẹ wọn buru.**

Ẹran Ara Ti O subu Jẹ Alaimọ

**Isaiah 64:6**

**Gbogbo wa si dabi ohun aimọ́, gbogbo ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin; gbogbo wa si rẹ̀ bi ewe; aiṣedede wa si mu wa kuro bi afẹfẹ.**

Iku Aiyeraiye mbẹ lori mi

**Romu 5:12**

**Nitoro gẹgẹ bi ẹ̀ṣẹ ti ti ipa ọdọ enia kan wọ̀ aiye, ati ikú nipa ẹ̀ṣẹ; bẽni ikú si kọja sori enia gbogbo, lati ọdọ ẹniti gbogbo enia ti dẹ̀ṣẹ.**

Ẹṣẹ Di Mi Ni'gbekun

**Romu 7:23**

**Ṣugbọn mo ri ofin miran ninu awọn ẹ̀ya ara mi, ti mba ofin inu mi jagun ti o si ndì mi ni igbekun wá fun ofin ẹ̀ṣẹ, ti o mbẹ ninu awọn ẹ̀ya ara mi.**

A da mi l'ẹbi

**Romu 5:18**

**Njẹ bi nipa ẹ̀ṣẹ kan idajọ de bá gbogbo enia si idalẹbi. . .**

Ẹṣẹ nfa Ipinya Pẹlu Ọlọrun

**Isaiah 59:2**

**Ṣugbọn aiṣedede nyin li o yà nyin kuro lọdọ Ọlọrun nyin. . .**

Ng O jihin Fun Ọlọrun

**Romu 14:12**

**Njẹ nitorina, olukuluku wa ni yio jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun.**

Ninu Ara ti O Subu, Mo Dabi Amọ, Koriko, Ikuuku

**Isaiah 64:8**

**Ṣugbọn nisisiyi, Oluwa, iwọ ni baba wa; awa ni àmọ, iwọ si ni ọ̀mọ; gbogbo wa si ni iṣẹ ọwọ́ rẹ.**

**I Peteru 1:24**

**Nitoripe Gbogbo ẹran ara dabi koriko, Ati gbogbo ogo rẹ̀ bi itanná koriko. Koriko a mã gbẹ, itanná rẹ̀ a si rẹ̀ silẹ.**

**Jakọbu 4:14**

**Nigbati ẹnyin kò mọ̀ ohun ti yio hù lọla. Kili ẹmí nyin? Ikũku sá ni nyin, ti o hàn nigba diẹ, lẹhinna a si túka lọ.**

Mo Le Ni Aiku Ati Iye Aiyeraiye ninu Kristi

**Johannu 11:25, 26**

**Jesu wi fun u pe, Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio kè: Ẹnikẹni ti o mbẹ lãye, ti o si gbà mi gbọ́, kì yio kú lailai. Iwọ gbà eyi gbọ́?**

**I Johannu 5:10, 11**

**Ẹniti o ba gbà Ọmọ Ọlọrun gbọ́, o ni ẹrí ninu ara rẹ̀: ẹniti kò ba gbà Ọlọrun gbọ́, o ti mu u li eke; nitori kò gbà ẹrí na gbó ti Ọlọrun jẹ niti Ọmọ rẹ̀. Ẹrí na si li eyi pe Ọlọrun fun wa ni ìye ainipẹkun, ìye yi si mbẹ ninu Ọmọ rẹ̀.**

**Orin Dafidi 24:7-10**

**Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu ọ̀na; Ki a si gbé nyin soke, ẹnyin ilẹkun aiyeraiye: Ọba ogo yio si wọ̀ inu ile lọ. Tali Ọba ogo yi? Oluwa ti o le, ti o si lagbara, Oluwa ti o lagbara li ogun. Ẹ gbé ori nyin soke, ẹnyin ẹnu ọ̀na; Ani ki ẹ gbé wọn soke, ẹnyin ilẹkun aiyeraiye: Ọba ogo yio si wọ̀ inu ile lọ. Tali Ọba ogo yi? Oluwa awọn ọmọ-ogun; On na li Ọba ogo.**

**I Timoteu 6:14-16**

**. . .titi di ifarahàn Oluwa wa Jesu Kristi. . . Ẹniti iṣe Olubukún ati Alagbara na kanṣoṣo, Ọba awọn ọba, ati Oluwa awọn oluwa; Ẹnikanṣoṣo ti o ni aikú, ti ngbe inu imọlẹ ti a kò le sunmọ, ẹniti enia kan kò ri rí ti kò si le ri: ẹniti ọla ati agbara titi lai iṣe tirẹ. Amin.**

Ọba yi yio jẹ Ọba Lori gbogbo aiye

**Sekariah 14:8, 9**

**Yio si ṣe li ọjọ na, omi iyé yio ti Jerusalemu ṣàn lọ, idajì wọn sihà òkun gabasi, ati idajì wọn sihà okun ẹhìn: nigbà ẹ̀run ati nigbà otutù ni yio ri bẹ̃. Oluwa yio si jọba lori gbogbo aiye: li ọjọ na ni Oluwa kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si jẹ ọkan.**

### Marku 14:61, 62

Ṣugbọn Jesu dakẹ, ko si dahùn ohun kan. Olori alufa si tun bi i lẽre, o wi fun u pe, Iwọ ni Kristi na, Ọmọ Olubukun nì? Jesu si wipe, Emi ni: ẹnyin o si ri Ọmọenia joko li ọwọ́ ọtún agbara, yio si ma ti inu awọsanma ọrun wá.

### Johannu 18:36, 37

Jesu dahùn wipe, Ijọba mi kì iṣe ti aiye yi: ibaṣepe ijọba mi iṣe ti aiye yi, awọn onṣẹ mi iba jà, ki a má bà fi mi le awọn Ju lọwọ: ṣugbọn nisisiyi ijọba mi kì iṣe lati ihin lọ. Nitorina Pilatu wi fun u pe, Njẹ iwọ ha ṣe ọba bi? Jesu dahùn wipe, Iwọ wipe, ọba li emi iṣe. Nitori eyi li a ṣe bí mi, ati nitori idi eyi ni mo si ṣe wá si aiye, ki emi ki o le jẹri si otitọ. Olukuluku ẹniti iṣe ti otitọ ngbọ́ ohùn mi.

### Matteu 25:31 ati 34

Nigbati Ọmọ-enia yio wá ninu ogo rẹ̀, ati gbogbo awọn angẹli mimọ́ pẹlu rẹ̀, nigbana ni yio joko lori itẹ́ ogo rẹ̀. . . Nigbana li Ọba yio wi fun awọn ti o wà li ọwọ́ ọtun rẹ pe, Ẹ wá, ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pèse silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa.

**Heberu 1:8**

Ṣugbọn niti Ọmọ li o wipe, Itẹ́ rẹ, Ọlọrun, lai ati lailai ni; Ọpá alade ododo li ọpá alade ijọba rẹ.

**Danieli 4:37**

Nisisiyi, emi Nebukadnessari yìn, mo si gbé Ọba ọrun ga, mo si fi ọlá fun u, ẹniti gbogbo iṣẹ rẹ̀ iṣe otitọ, ati gbogbo ọ̀na rẹ̀ iṣe ẹtọ: ati awọn ti nrìn ninu igberaga, on le rẹ̀ wọn silẹ.

**Matteu 18:3, 4**

O si wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin kì yio le wọle ijọba ọrun. Nitorina ẹnikẹni ti o ba rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ bi ọmọ kekere yi, on na ni yio papọ̀ju ni ijọba ọrun.

**Ifihàn 11:15**

. . .Ijọba aiye di ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ̀; on o si jọba lai ati lailai.

**Orin 22:28**

Nitori ijọba ni ti Oluwa; On si Bãlẹ ninu awọn orilẹ-ède.

**Efesu 1:18, 19**

Ki oju ọkàn nyin le mọlẹ; ki ẹnyin ki o le mọ ohun ti ireti ìpe rẹ̀ jẹ, ati ohun ti orọ̀ ogo ini rẹ̀ ninu awọn enia mimọ́ jẹ, Ati agbara rẹ̀ ti o tobi julọ si awa ti o gbagbọ́, gẹgẹ bi iṣẹ agbara rẹ̀.

Johannu 17:2

Gẹgẹ bi iwọ ti fun u li aṣẹ lori enia gbogbo, ki o le fi iye ainipẹkun fun gbogbo awọn ti o fifun u.

I Peteru 3:22

Ẹniti o ti lọ si ọrun, ti o si mbẹ li ọwọ́ ọtún Ọlọrun; ori awọn angẹli, ati awọn ọlọlá, ati awọn alagbara si ntẹriba fun.

Efesu 1:20-23

Eyiti o ti ṣiṣẹ ninu Kristi, nigbati o ti jí dide kuro ninu okú, ti o si fi i joko li ọwọ́ ọtún ninu awọn ọrun, Ga ju gbogbo ijọba ati ọla, ati agbara, ati oyé, ati gbogbo orukọ ti a ndá, ki iṣe li aiye yi nikan, ṣugbọn li eyiti mbọ̀ pẹlu. O si ti fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ̀, o si ti fi i ṣe ori lori ohun gbogbo fun ijọ, Eyiti iṣe ara rẹ̀, ẹ̀kún ẹniti o kún ohun gbogbo ninu ohun gbogbo.

Johannu 2:24, 25

Ṣugbọn Jesu kò gbé ara le wọn, nitoriti o mọ̀ gbogbo enia. On ko si wa ki ẹnikẹni ki o jẹri enia fun on: nitoriti on mọ̀ ohun ti mbẹ ninu enia.

Johannu 17:23

Emi ninu wọn, ati iwọ ninu mi, ki a le sẹ wọn pé li ọ̀kan; ki aiye ki o le mọ̀ pe, iwọ li o rán mi, ati pe iwọ si fẹràn wọn gẹgẹ bi iwọ ti fẹràn mi.

**Ifihàn 5:12**

. . .Yiyẹ, li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún.

**Matteu 28:18**

Jesu si wá, o si sọ fun wọn, wipe, Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi.

**I Korinti 8:6**

Ṣugbọn fun awa Ọlọrun kan ni mbẹ, Baba, lọwọ ẹniti ohun gbogbo ti wá, ati ti ẹniti gbogbo wa iṣe; ati Oluwa kanṣoṣo Jesu Kristi, nipasẹ ẹniti ohun gbogbo wà, ati awa nipasẹ rẹ̀.

**I Korinti 1:24**

Ṣugbọn fun awọn ti a pè, ati Ju ati Griki, Kristi li agbara Ọlọrun, ati ọgbọ́n Ọlọrun.

**Ifihàn 11:17**

Wipe, Awa fi ọpẹ́ fun ọ, Oluwa Ọlọrun, Olodumare, ti mbẹ, ti o si ti wà, ti o si ma bọ̀; Nitoriti iwọ ti gbà agbara nla rẹ, iwọ si ti jọba.

**Kolosse 2:2, 3**

Ki a le tu ọkàn wọn ninu, bi a ti so wọn pọ̀ ninu ifẹ ati si gbogbo ọrọ̀ ẹ̀kún oye ti o daju, si imọ̀ ohun ijinlẹ Ọlọrun ani Kristi; Inu ẹniti a ti fi gbogbo iṣura ọgbọ́n ati ti ìmọ pamọ́ si.

### Orin 72:8, 9 ati 11

On o si jọba lati okun de okun, Ati lati Odò nì de opin ilẹ-aiye. Awọn ti o joko li aginju yio tẹati tiriba fun u; Awọn ọta rè yio si lá erupẹ ilẹ. . . . Nitõtọ, gbogbo awọn ọba ni yio wolẹ niwaju rè: Gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma sìn i.

### Orin 2:2-4 ati 6-8

Awọn ọba aiye kẹsẹ jọ, Ati awọn ijoye ngbimọ pọ̀ Si Oluwa ati si Ẹni-ororo rẹ̀ pe, Ẹ jẹ ki a fa ìde wọn, jà, Ki a si mu okùn wọn kuro li ọdọ wa. Ẹniti o joko li ọrun yio rẹrin: Oluwa yio yọ ṣùti si wọn. . . Ṣugbọn mo ti fi Ọba mi jẹ Lori Sioni, òke mimọ́ mi. Emi ó si rohin ipinnu Oluwa: O ti wi fun mi pe, Iwọ li Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ. Bère lọwọ mi, emi o si fi awọn orilẹède fun ọ ni ini rẹ, Ati iha opin ilẹ li ọrò-ilẹ rẹ.

### Jeremiah 10:7 ati 10

Tani kì ba bẹru rẹ, iwọ Ọba orilẹ-ède? nitori tirẹ ni o jasi; kò si ninu awọn ọlọgbọ́n orilẹ-ède, ati gbogbo ijọba wọn, kò si ẹniti o dabi iwọ! . . .Ṣugbọn Oluwa, Ọlọrun otitọ ni; on ni Ọlọrun alãye, ati Ọba aiyeraiye! aiye yio warìri nigbati o ba binu, orilẹède kì yio le duro ni ibinu rẹ̀. ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo nla.

**Isaiah 42:8**

**Emi li Oluwa: eyi ni orukọ mi: ogo mi li emi kì yio fi fun ẹlòmiran, bẽni emi kì yio fi iyìn mi fun ere gbigbẹ.**

**Orin 95:3**

**Nitori Oluwa, Ọlọrun ti o tobi ni, Ati Ọba ti o tobi jù gbogbo orişa lọ.**

**Matteu 24:30**

**Nigbana li àmi Ọmọ-enia yio si fi ara hàn li ọrun; nigbana ni gbogbo ẹya aiye yio kãnu, nwọn o si ri Ọmọ-enia ti yio ma ti oju ọrun bọ̀ ti on ti agbara ati ogo nla.**

**Ifihàn 4:11**

**Oluwa, iwọ li o yẹ Lati gbà ogo ati ọlá ati agbara: Nitoripe iwọ li o dá ohun gbogbo, Ati nitori ifẹ inu rẹ ni nwọn fi wà ti a si dá wọn.**

**1 Timoteu 1:17**

**Njẹ fun Ọba aiyeraiye, aidibajẹ, airi, Ọlọrun kanşoşo, ni ọlá ati ogo wà fun lai ati lailai. Amin.**

Yio Se Ajọpin Ogo Rẹ Pẹlu Iyawo Rẹ

**Johannu 17:22**

**Ogo ti iwọ ti fifun mi li emi si ti fifun wọn; ki nwọn ki o le jẹ ọ̀kan, gẹgẹ bi awa ti jẹ ọ̀kan.**

**Romu 8:18**

**Nitori mo şìro rè̩ pe, iya igba isisiyi kò yẹ lati fi şe akawe ogo ti a o fihàn ninu wa.**

**Isaiah 9:7**
**Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹkun. . .**

**Isaiah 45:9-13**
**Egbe ni fun ẹniti o mbá Ẹlẹda rẹ̀ ja, apãdi ninu awọn apãdi ilẹ! . . . Egbe ni fun ẹniti o wi fun baba rẹ̀ pe, Kini iwọ bi? tabi fun obirin ni pe, Kini iwọ bi? Bayi li Oluwa wi, Ẹni-Mimọ Israeli, ati Ẹlẹda rẹ̀, Bere nkan ti mbọ̀ lọwọ mi, niti awọn ọmọ mi ọkunrin, ati niti iṣẹ ọwọ mi, ẹ paṣẹ fun mi. Mo ti dá aiye, mo si ti da enia sori rẹ̀; Emi, ani ọwọ́ mi, li o ti nà awọn ọrun, gbogbo awọn ogun wọn ni mo si ti paṣẹ fun. Mo ti gbe e dide ninu ododo, emi o si mu gbogbo ọna rẹ̀ tọ́. . .**

**Danieli 7:14**
**A si fi agbara ijọba, ati ogo, ati ijọba fun u, ki gbogbo enia, ati orilẹ, ati ède, ki o le ma sìn i; agbara ijọba rẹ̀ si jẹ agbara ijọba ainipẹkun, eyiti a kì yio rekọja, ati ijọba rẹ̀, eyiti a kì yio le parun.**

Se Igbọran Si Aṣẹ Rẹ!

**Orin Dafidi 72:11**
**Nitõtọ, gbogbo awọn oba ni yio wole niwaju rẹ̀: Gbogbo awọn orilẹ-ède ni yio ma sìn i.**

Sọ asọtẹlẹ ibi ati iru iku ati Ajinde

**Matteu 20:18, 19**

**Wò o, awa ngoke lọ si Jerusalemu; a o si fi Ọmọ-enia le awọn olori alufa, ati awọn akọwe lọwọ, nwọn o si da a lẹbi ikú. Nwọn o si fà a le awọn Keferi lọwọ lati fi i ṣe ẹlẹyà, lati nà a, ati lati kàn a mọ agbelebu: ni ijọ kẹta yio si jinde.**

Ẹsẹ Buru Loju Ọlọrun To Bẹẹ Gẹ Ti O Fi pe fun iru atunse yi

**I Peteru 3:18**

**Nitoriti Kristi pẹlu jìya lẽkan nitori ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ fun awọn alaiṣõtọ, ki o le mu wa de ọdọ Ọlọrun, ẹniti a pa ninu ara, ṣugbọn ti a sọ di ãye ninu ẹmi.**

**Galatia 1:3, 4**

**. . .ati Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹniti o fi on tikalarẹ̀ fun ẹ̀ṣẹ wa, ki o le gbà wa kuro ninu aiye buburu isisiyì gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun ati Baba wa.**

**I Johannu 3:16**

**Nipa eyi li awa mọ̀ ifẹ, nitoriti o fi ẹmí rẹ̀ lelẹ fun wa. . .**

**I Korinti 1:18**

**Nitoripe wère li ọ̀rọ agbelebu si awọn ti o nṣegbé; ṣugbọn si awa ti a ngbalà, agbara Ọlọrun ni.**

**Efesu 2:13**

Ṣugbọn nisisiyi ninu Kristi Jesu ẹnyin ti o ti jìna réré nigba atijọ rí li a mu sunmọ tosi, nipa èjẹ Kristi.

**Heberu 10:19, 20**

Ará, njẹ bi a ti ni igboiya lati wọ inu ibi mimọ nipasẹ èjẹ Jesu, Nipa ọna titun ati ãye. . .

**Heberu 13:20**

. . .nipa èjẹ majẹmu aiyeraiye. . .

**I Peteru 2:6, 7**

. . .iyebiye, lelẹ ni Sioni: Ẹniti o ba si gbà a gbọ oju kì yio ti i. Nitorina fun ẹnyin ti o gbagbọ, ọla ni. . .

**Kolosse 1:20**

Ati nipasẹ rẹ lati bá ohun gbogbo lajà. . .

**Ifihàn 1:5**

. . .Ẹniti o fẹ wa, ti o si wẹ wa ninu èjẹ rẹ kuro ninu ẹṣẹ wa.

**II Timoteu 3:15**

Ati pe lati igba ọmọde ni iwọ ti mọ iwe-mimọ, ti o le sọ ọ di ọlọgbọn si igbala nipasẹ igbagbọ ninu Kristi Jesu.

Ọkọ iyawo nwa Iyawo Rẹ

**Luku 19:10**

Nitori Ọmọ-enia de lati wà awọn ti o nù kiri, ati lati gbà wọn là.

# KRISTI ṢEGUN IKU KEJI ATI ỌRUN APAADI LATI GBA MI LỌWỌ WỌN

Iku aiyeraiye Ni O Tọ Si Mi

**Esekieli 18:4**

**. . .ọkàn ti o bá ṣè, on o kú.**

**Romu 5:12**

**Nitori gẹgẹ bi èṣẹ ti ti ipa ọdọ enia kan wọ aiye, ati ikú nipa èṣẹ; bẽni ikú si kọja sori enia gbogbo, lati ọdọ ẹniti gbogbo enia ti dèṣẹ.**

**Romu 6:23**

**Nitori ikú li ère èṣẹ. . .**

A ṣegun iku fun mi

**II Timoteu 1:8-10**

**Nitorina máṣe tiju ẹrí Oluwa wa, tabi emi ondè rè: ṣugbọn ki iwọ ki o ṣe alabapin ninu ipọnju ihinrere gẹgẹ bi agbara Ọlọrun; Ẹniti o gbà wa là, ti o si fi ìpe mimọ pè wa, kì iṣe gẹgẹ bi iṣe wa, ṣugbọn gẹgẹ bi ipinnu ati ore-ofẹ tirè, ti a fifun wa ninu Kristi Jesu lati aiyeraiye, Ṣugbọn ti a fihàn nisisiyi nipa ifarahàn Jesu Kristi Olugbala wa, ẹniti o pa ikú ré, ti o si mu ìye ati aidibajẹ wá si imọlẹ nipasẹ ihinrere.**

**Ifihàn 1:18**

**Emi li ẹniti o mbẹ lãye, ti o si ti kú; si kiyesi i, emi si mbẹ lãye si i titi lai, Amin; mo si ni kọkọrọ ikú ati ti ipo-oku.**

# 18 ỌBA NAA PESE IGBALA ỌFẸ FUN GBOGBO ẸNITI O BA FẸẸ TỌKANTỌKAN

**I Korinti 15:3**
. . .bi Kristi ti kù nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwemimọ́ ti wi.

**Iṣe 20:28**
. . .lati mã tọju ijọ Ọlọrun, ti o ti fi ẹ̀jẹ ara rẹ rà.

**Johannu 10:11**
Emi ni oluṣọ-agutan rere: oluṣọ-agutan rere fi ẹmí rẹ̀ lelẹ nitori awọn agutan.

**II Korinti 5:15**
O si ti kú fun gbogbo wọn, pe ki awọn ti o wà lãye ki o má si ṣe wà lãye fun ara wọn mọ́, bikoṣe fun ẹniti o kú nitori wọn, ti o si ti jinde.

**Iṣe 10:43**
On ni gbogbo awọn woli jẹri si pe, nipa orukọ rẹ̀ li ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ gbà.

**II Peteru3:9**
Oluwa kò fi ileri rẹ jafara, bi awọn ẹlomiran iti kà ijafara; ṣugbọn o nmu sũru fun nyin nitori kò fẹ ki ẹnikẹni ki o ṣegbé, bikoṣe ki gbogbo enia ki o wá si ironupiwada.

**Jeremiah 29:13**
Ẹnyin o si ṣafẹri mi, ẹ o si ri mi, nitori ẹ o fi gbogbo ọkàn nyin wá mi.

### Orin Dafidi 45:6, 7

Ọlọrun, lai ati lailai ni itẹ́ rẹ: Ọpá-alade ijọba rẹ ọpá-alade otitọ ni. Iwọ fẹ ododo, iwọ korira ìwa buburu. . .

### I Korinti 6:9-10

Ẹnyin kò mọ̀ pe awọn alaiṣõtọ kì yio jogún ijọba Ọlọrun? Ki a a má tàn nyin jẹ: kì iṣe awọn àgbere, tabi awọn abọriṣa, tabi awọn panṣaga, tabi awọn alailera, tabi awọn ti nfi ọkunrin bà ara wọn jẹ́, Tabi awọn olè, tabi awọn olojukòkoro, tabi awọn ọmuti, tabi awọn ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọwọgbà ni yio jogún ijọba Ọlọrun.

### Romu 8:5-8

Nitori awọn ti o wà nipa ti ara, nwọn a mã ro ohun ti ara; ṣugbọn awọn ti o wà nipa ti Ẹmí, nwọn a mã ro ohun ti Ẹmí. Nitori ero ti ara ikú ni; ṣugbọn ero ti Ẹmí. ni iye ati alafia: Nitori ero ti ara ọtá ni si Ọlọrun: nitori ki itẹrba fun ofin Ọlọrun, on kò tilẹ le ṣẹ e. Bẽli awọn ti o wà ninu ti ara, kó le wù Ọlọrun.

### Jakọbu 4:4

Ẹnyin panṣaga ọkunrin, ati panṣaga obirin, ẹ kò mọ̀ pe ìbaré aiye ìṣọtá Ọlọrun ni? nitorina ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ́ ọrẹ aiye di ọtá Ọlọrun.

**Owe 28:13**

Ẹniti o bo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọlẹ kì yio ṣe rere: Ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ ti o si kọ̀ ọ silẹ yio ri ãnu.

**I Johannu 4:16**

Awa ti mọ̀ a si gbà ifẹ ti Ọlọrun ni si wa gbọ́. Ifẹ ni Ọlọrun; ẹniti o ba si ngbé inu ife o ngbé inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀.

**Johannu 1:12**

Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun. . .

**Johannu 13:20**

. . .ẹniti o ba si gbà mi o gbà ẹniti o rán mi.

**Iṣe 8:36, 37**

Bi nwọn si ti nlọ li ọ̀na, nwọn de ibi omi kan: iwẹfa na si wipe, Wò o, omi niyi; kili o dá mi duro lati baptisi? Filippi si wipe, Bi iwọ ba gbagbọ́ tọkàntọkan, a le baptisi rẹ. . .

**I Korinti 2:5**

Ki igbagbọ́ nyin ki o máṣe duro ninu ọgbọ́n enia, bikoṣe ninu agbara Ọlọrun.

**Johannu 8:31**

Nitorina Jesu wi fun awọn Ju ti o gbà a gbọ́ pe, Bi ẹnyin ba duro ninu ọ̀rọ mi, nigbana li ẹnyin jẹ ọmọ-ẹhin mi nitõtọ.

**Efesu 3:19**

Ati lati mọ ifẹ Kristi ti o ta ìmọ yọ, ki a le fi gbogbo ẹ̀kún Ọlọrun kun nyin.

**Romu 8:10**

Bi Kristi ba si wà ninu nyin, ara jẹ okú nitori ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹmí jẹ iyè nitori ododo.

**Johannu 10:14, 15**

Emi ni aluṣọ-agutan rere, mo si mọ̀ awọn temi, awọn temi si mọ̀ mi. Gẹgẹ bi Baba ti mọ̀ mi, ti emi si mọ̀ Baba: mo si fi ẹmí mi lelẹ nitori awọn agutan.

**Johannu 10:26-28**

Ṣugbọn ẹnyin kò gbagbọ́, nitori ẹnyin kò si ninu awọn agutan mi, gẹgẹ bi mo ti wi fun nyin. Awọn agutan mi ngbọ ohùn mi, emi si mọ̀ wọn, nwọn a si ma tọ̀ mi lẹhin: Emi si fun wọn ni ìye ainipẹkun; nwọn kì o si ṣegbé lailai, kò si si ẹniti o le já wọn kuro li ọwọ́ mi.

**II Timoteu 1:12**

Nitori idi eyiti emi ṣe njìya wọnyi pẹlu: ṣugbọn oju kò tì mi: nitori emi mọ̀ ẹniti emi gbagbọ́, o si da mi loju pe, on le pa ohun ti mo fi le e lọwọ mọ́ titi di ọjọ nì.

**I Peteru 4:19**

Nitorina ẹ jẹ ki awọn ti njìya gẹgẹ bi ifẹ Ọlọrun, fi ọkàn wọn le e lọwọ pẹlu ni rere iṣe, bi ẹnipe fun Ẹlẹda olõtọ.

**I Johannu 5:5**

Tani ẹniti o ṣẹgun aiye, bikoṣe ẹniti o gbagbọ́ pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu iṣe?

**Johannu 1:13**

Awọn ẹniti a bí, kì iṣe nipa ti èjẹ, tabi nipa ti ifẹ ara, bẽni kì iṣe nipa ifẹ ti enia, bikoṣe lati ọwọ Ọlọrun.

**II Korinti 3:17**

Njẹ Oluwa li Ẹmí na: nibiti Ẹmí Oluwa ba si wà, nibẹ̀ li omnira gbé wà.

**Romu 6:18 ati 22**

Bi a si ti sọ nyin di omnira kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ẹnyin di ẹrú ododo. . . .Ṣugbọn nisisiyi ti a sọ nyin di omnira kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ti ẹnyin si di ẹrú Ọlọrun, ẹnyin ni eso nyin si ìwa mimọ́, ati opin rẹ̀ ìye ainipẹkun.

**Johannu 8:32**

Ẹ ó si mọ̀ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di omnira.

**Johannu 8:36**

Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di omnira, ẹ ó di omnira nitõtọ.

**Galatia 5:1**

NITORINA ẹ duro ṣinṣin ninu omnira na eyi ti Kristi fi sọ wa di omnira, ki ẹ má si ṣe tún fi ọrùn bọ àjaga ẹrú mọ́.

**Iṣe 22:15**

Ki iwọ ki o le ṣe ẹlẹri rẹ̀ fun gbogbo enia, li ohun ti iwọ ti ri ti iwọ si ti gbọ́.

### I Korinti 6:2

Ẹnyin kò ha mọ̀ pe awọn enia mimọ́ ni yio ṣe idajọ aiye?. . .

### Ifihàn 1:5, 6

Ati lati ọdọ Jesu Kristi, ẹlẹri olõtọ, akọbi ninu awọn okú, ati alaṣẹ awọn ọba aiye. . .Ti o si ti fi wa jẹ́ ọba ati alufa fun Ọlọrun ati Baba rẹ̀; tirẹ̀ li ogo ati ijọba lai ati lailai. Amin.

### I Korinti 6:9-11

Ẹnyin kọ mọ̀ pe awọn alaiṣõtọ kì yio jogún ijọba Ọlọrun? Ki a má tàn nyin jẹ: kì iṣe awọn àgbere, tabi awọn abọriṣa, tabi awọn panṣage, tabi awọn alailera, tabi awọn ti nfi ọkunrin bà ara wọn jẹ́, Tabi awọn olè, tabi awọn olojukòkoro, tabi awọn ọmuti, tabi awọn ẹlẹgàn, tabi awọn alọnilọwogbà ni yio jogún ijọba Ọlọrun. Bẽ li awọn ẹlomiran ninu nyin si ti jẹ rí: ṣugbọn a ti sọ nyin di mimọ́, ṣugbọn a ti da nyin lare li orukọ Jesu Kristi Oluwa, ati nipa Ẹmí Ọlọrun wa.

### Isaiah 62:3

Iwọ o jẹ ade ogo pẹlu li ọwọ́ Oluwa, ati lawani ọba li ọwọ́ Ọlọrun rẹ.

Ipo ti a gbega

### Johannu 17:21

Ki gbogbo nwọn ki o le jẹ ọ̀kan; gẹgẹ bi iwọ, Baba, ti jẹ ninu mi, ati emi ninu rẹ, ki awọn pẹlu ki o le jẹ ọ̀kan ninu wa. . .

**Orin 145:18**

Oluwa wà leti ọdọ gbogbo awọn ti nkepè e, Leti ọdọ gbogbo eniti nkepè e li otitọ.

**II Korinti 6:16**

Irẹpọ̀ kini tẹmpili Ọlọrun si ni pẹlu orișa? nitori ẹnyin ni tẹmpili Ọlọrun alãye; gẹgẹ bi Ọlọrun ti wipe, Emi ó mã gbé inu wọn, emi o si mã rìn ninu wọn; Emi o si jẹ Ọlọrun wọn, Nwọn o si jẹ enia mi.

**I Peteru 4:13**

Șugbọn niwọnbi ẹnyin ti jẹ alabapin ìya Kristi, ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o le yọ̀ ayọ̀ pipọ nigbati a ba fi ogo rẹ̀ hàn.

**I Johannu 1:3**

. . .nitõto ìdapọ wa si mbẹ pẹlu Baba, ati pẹlu Ọmọ rẹ̀ Jesu Kristi.

**Isaiah 43:2**

Nigbati iwọ ba nlà omi kọja, emi o pẹlu rẹ; ati lãrin odò, nwọn ki yio bò ọ mọlẹ: nigbati iwọ ba nrìn ninu iná, ki yio jo ọ, bẽni ọwọ́-iná ki yio ràn ọ.

**Johannu 17:23**

Emi ninu wọn, ati iwọ ninu mi, ki a le șe wọn pé li ọ̀kan; ki aiye ki o le mọ̀ pe, iwọ li o rán mi, ati pe iwọ si fẹràn wọn gẹgẹ bi iwọ ti fẹràn mi.

**Johannu 14:20**

**Li ọjọ na li ẹnyin o mọ̀ pe, emi wà ninu Baba mi, ati ẹnyin ninu mi, ati emi ninu nyin.**

**Johannu 15:5**

**Emi ni àjara, ẹnyin li ẹká. Ẹniti o ngbé inu mi, ati emi ninu rè, on ni yio so eso ọ̀pọlọpọ: nitori ni yiyara nyin kuro lọdọ mi, ẹ ko le ṣe ohun kan.**

Aṣẹ Rẹ Ikẹhin Aniyan wa akọkọ

**Ifihàn 22:17**

**Ati Ẹmí ati iyawo wipe, Mã bọ̀. . .**

**Matteu 28:19, 20**

**Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, ki ẹ si ma baptisi wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmí Mimọ́: Ki ẹ ma kọ́ wọn lati ma kiyesi ohun gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin: ẹ si kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo, titi o fi de opin aiye. Amin.**

Ododo Awọn Mimọ jẹ ododo Kristi Ti O Ngbe Inu Wọn

**Kolosse 1:27**

**Awọn ẹniti Ọlọrun fẹ lati fi orọ̀ ohun ijinlẹ yi larin awọn Keferi hàn fun, ti iṣe Kristi ninu nyin, ireti ogo.**

**Romu 10:4**

**Nitori Kristi li opin ofin si ododo fun olukuluku ẹniti o gbagbọ́.**

# AANU GIGA, IFẸ GIGA ATI OORE-ỌFẸ GIGA

**I Peteru 1:3**

Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹniti o tún wa bi, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀, sinu ireti ãye nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu okú.

**Heberu 4:16**

Nitorina ẹ jẹ ki a wá si ibi itẹ ore-ọfẹ pẹlu igboiya, ki a le ri ãnu gbà, ki a si ri ore-ọfẹ lati mã ràn-ni-lọwọ ni akoko ti o wọ̀.

**Efesu 2:4-7**

Ṣugbọn Ọlọrun, ẹniti iṣe ọlọrọ̀ li ãnu, nitori ifẹ nla rẹ̀ ti o fi fẹ wa, Nigbati awa tilẹ ti kú nitori ẹṣẹ wa, o sọ wa di ãye pẹlu Kristi (ore-ọfẹ li a ti fi gba nyin là). O si ti ji wa dide pẹlu rẹ̀, o si ti mu wa joko pẹlu rẹ̀ ninu awọn ọrun ninu Kristi Jesu: Pe ni gbogbo ìgba ti mbọ ki o ba le fi ọrọ̀ ore-ọfẹ rẹ̀ ti o pọ rekọja han ninu iṣeun rẹ̀ si wa ninu Kristi Jesu.

**I Peteru 5:10**

Ọlọrun ore-ọfẹ gbogbo, ti o ti pè nyin sinu ogo rẹ̀ ti kò nipẹkun ninu Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba ti Jìya diẹ, On tikarãrẹ, yio si ṣe nyin li aṣepé, yio fi ẹsẹ nyin mulẹ, yio fun nyin li agbara, yio fi idi nyin kalẹ.

**Romu 3:24**

Awọn ẹniti a ndalare lọfẹ nipa ore-ọfẹ rẹ̀, nipa idande ti o wà ninu Kristi Jesu.

**Galatia 4:4, 5**

Ṣugbọn nigbati akokò kikum na de, Ọlọrun rán Ọmọ rè jade wá, ẹniti a bí ninu obirin, ti a bí labẹ ofin, Lati ra awọn ti mbẹ labẹ ofin pada, ki awa ki o le gbà isọdọmọ.

**I Johannu 3:1**

Ẹ WO irú ifẹ ti Baba fi fẹ wa, ti a fi npè wa ni ọmọ Ọlọrun. . .

Arole Ọlọrun

**Galatia 4:6, 7**

Ati nitoriti ẹnyin nṣe ọmọ, Ọlọrun si ti rán Ẹmí Ọmọ rè wá sinu ọkàn nyin, ti nke pe, Abba, Baba. Nitorina iwọ kì iṣe ẹru mọ, bikoṣe ọmọ, ati bi iwọ ba iṣe ọmọ, njẹ iwọ di arolé Ọlọrun nipasẹ Kristi.

**Ifihàn 21:7**

Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi; emi o si mã jẹ Ọlọrun rè, on o si mã jẹ ọmọ mi.

**Romu 8:17**

Bi awa ba si jẹ ọmọ, njẹ ajogun li awa, ajogun Ọlọrun, ati ajumọ-jogun pẹlu Kristi; biobaṣepe awa bá a jìya, ki a si le ṣe wa logo pẹlu rè.

**Galatia 3:29**

Bi ẹnyin ba si jẹ ti Kristi, njẹ ẹnyin ni irú-ọmọ Abrahamu, ati arole gẹgẹ bi ileri.

**Romu 8:28, 29**

**Awa si mọ̀ pe ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti a pè gẹgẹ bi ipinnu rẹ̀. Nitori awọn ẹniti o ti mọ̀ tẹlẹ, li o si ti yàn tẹlẹ lati ri bi aworan Ọmọ rẹ̀, ki on le jẹ akọbi larin awọn arakunrin pupọ.**

Sin gẹgẹbi Kristi

**Luku 22:27**

**. . .ṣugbọn emi mbẹ larin nyin bi ẹniti nṣe iranṣẹ.**

Maa dariji

**Luku 23:34**

**Jesu si wipe, Baba, dariji wọn; nitoriti nwọn kò mọ̀ ohun ti nwọn nṣe. . .**

Jẹ onirẹlẹ ati oniwapẹlẹ

**II Korinti 10:1**

**Ṣugbọn emi Paulu tikarami fi inu tutù ati ìwa pẹlẹ Kristi bẹ̀ nyin. . .**

Maa rin ninu ifẹ Kristi

**Johannu 15:9**

**Gẹgẹ bi Baba ti fẹ mi, bẽli emi si fẹ nyin: ẹ duro ninu ifẹ mi.**

Tan ihinrere kaakiri agbaiye

**Johannu 20:21**

**Nitorina Jesu si tún wi fun wọn pe, Alafia fun nyin: gẹgẹ bi Baba ti rán mi, bẽli emi si rán nyin.**

**I Tessalonika 2:12**

**Ki ẹnyin ki o le mã rìn ni yiyẹ Ọlọrun, ẹniti o npè nyin sinu ijọba ati ogo On tikararẹ.**

**II Johannu 9**

**Olukuluku ẹniti o ba nru ofin ti kò si duro ninu ẹkọ́ Kristi, kò gba Ọlọrun. Ẹniti o ba duro ninu ẹkọ́, on li o gbá ati Baba ati Ọmọ.**

Kristi yio ni Iyawo ti a ko le fi ẹtan gba kuro lọdọ Rẹ

**Jakọbu 1:12**

**Ibukún ni fun ọkunrin ti o fi ọkàn rán idanwò: nitori nigbati o ba yeje, yio gbà ade ìye, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ.**

**Luku 6:47, 48**

**Ẹnikẹni ti o tọ̀ mi wá, ti o si ngbọ́ ọ̀rọ mi, ti o si nṣe e, emi o fi ẹniti o jọ hàn nyin: O jọ ọkunrin kan ti o kọ́ ile, ti o si walẹ jìn, ti o si fi ipilẹ sọlẹ lori apata: nigbati kíkun omi de, igbiomi bilù ile na, kò si le mì i: nitoriti a fi ipilẹ rẹ̀ sọlẹ lori apata.**

Ti O Si Nfojusọna fun Wiwa Rẹ

**Titu 2:13**

**Ki a mã wo ọna fun ireti ti o ni ibukún ati ifarahan ogo Ọlọrun wa ti o tobi, ati ti Olugbala wa Jesu Kristi.**

**I Korinti 2:5**

**Ki igbagbọ́ nyin ki o máṣe duro ninu ọgbọ́n enia, bikoṣe ninu agbara Ọlọrun.**

**Efesu 3:20, 21**

**Njẹ ẹniti o le ṣe lọpọlọpọ jù gbogbo eyiti a mbère tabi ti a nrò lọ, gẹgẹ bi agbara ti nṣiṣẹ ninu wa, On ni ki a mã fi ogo fun ninu ijọ ati ninu Kristi Jesu titi irandiran gbogbo, aiye ainipẹkun. Amin.**

**Efesu 2:8-10**

**Nitori ore-ọfẹ li a ti fi gbà nyin là nipa igbagbọ́; ati eyini kì iṣe ti ẹnyin tikaranyin: ẹ̀bun Ọlọrun ni: Kì iṣe nipa iṣẹ ki ẹnikẹni má bã ṣogo. Nitori awa ni iṣẹ ọwọ́ rẹ̀ ti a ti dá ninu Kristi Jesu fun iṣẹ rere, ti Ọlọrun ti pèse tẹlẹ, ki awa ki o le mã rìn ninu wọn.**

A o see ni yiyẹ ati pipe ninu Rẹ

**Efesu 4:13**

**Titi gbogbo wa yio fi de iṣọkan igbagbọ́ ati ìmọ Ọmọ Ọlọrun, titi a o fi di ọkunrin, titi a o fi de iwọn gigun ẹ̀kún Kristi.**

**Kolosse 2:9, 10**

**Nitoripe ninu rẹ̀ ni gbogbo ẹ̀kún Iwa-Ọlọrun ngbé li araiyara. A si ti ṣe nyin ni kikún ninu rẹ̀, ẹniti iṣe ori fun gbogbo ijọba ati agbara.**

Kini idi rẹ ti Ẹniti awọn aimoye angẹli nsin fi nilati doju ifẹ Rẹ kọ ọlọtẹ eniyan ti o subu?

**Heberu 1:6**

**Ati pẹlu, nigbati o mu akọbi ni wá si aiye, o wipe, Ki gbogbo awọn angẹli Ọlọrun ki o foribalẹ fun u.**

**Owe 8:31**

**. . .Didùn-inu mi si wà sipa awọn ọmọ enia.**

**Romu 12:4, 5**

**Nitori gẹgẹ bi awa ti li ẹya pipọ ninu ara kan, ti gbogbo ẹya kò si ni iṣẹ kanna: Bẽli awa, ti a jẹ pipọ, a jẹ ara kan ninu Kristi, ati olukuluku ẹya ara ọmọnikeji rẹ.**

**Romu 7:4**

**. . .ẹnyin pẹlu ti di okú si ofin nipa ara Kristi; ki ẹnyin kì o le ni ẹlomiran, ani ẹniti a jinde kuro ninu okú, ki awa ki o le so eso fun Ọlọrun.**

Iyawo gba Iye lati ọdọ Rẹ

**I Johannu 5:12**

**Ẹniti o ba ni Ọmọ, o ni ìye; ẹniti kò ba si ni Ọmọ Ọlọrun, kò ni ìye.**

Ifẹ afẹtan fun Iyawo

**Romu 8:32**

**Ẹniti kò da Ọmọ on tikararẹ si, ṣugbọn ti o jọwọ rẹ lọwọ fun gbogbo wa, yio ha ti ṣe ti kì yio fun wa li ohun gbogbo pẹlu rẹ lọfẹ?**

Pin itẹ pẹlu iyawo

**Ifihàn 3:21**

**Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ̀.**

Ilu Ọba naa ati Iyawo

**Heberu 11:16**

**Ṣugbọn nisisiyi nwọn nfẹ ilu kan ti o dara jù bẽ lọ, eyini ni ti ọ̀run: nitorina oju wọn kò ti Ọlọrun, pe ki a mã pe On ni Ọlọrun wọn; nitoriti o ti pèse ilu kan silẹ fun wọn.**

**Ifihàn 3:12**

**Ẹniti o ba ṣẹgun, on li emi o fi ṣe ọwọ̀n ninu tẹmpili Ọlọrun mi, on kì yio si jade kuro nibẹ mọ́: emi o si kọ orukọ Ọlorun mi si i lara, ati orukọ ilu Ọlọrun mi, ti iṣe Jerusalemu titun, ti o nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun mi wá. . .**

**Ifihàn 21:2**

**Mo si ri ilu mimọ́ nì, Jerusalemu titun nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun wá, ti a mura silẹ bi iyawo ti a ṣe lọṣọ́ fun ọkọ rẹ́.**

**Ifihàn 22:14**

**Ibukún ni fun awọn ti nfọ̀ aṣọ wọn, ki nwọn ki o le ni anfani lati wá si ibi igi ìye na, ati ki nwọn ki o le gba awọn ẹnubode wọ inu ilu na.**

**Luku 16:11**
**Nję bi ẹnyin kò ba ti jẹ olõtọ ni mammoni aiṣõtọ, tani yio fi ọrọ̀ tõtọ ṣú nyin?**

**II Korinti 8:9**
**Nitori ẹnyin mọ̀ oreọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi, pe bi on ti jẹ ọlọrọ̀ rí, ṣugbọn nitori nyin o di talaka, ki a le sọ nyin di ọlọrọ̀ nipa aini rẹ̀.**

**Jakọbu 2:5**
**Ẹ fi etí silẹ, ẹnyin ará mi olufẹ, Ọlọrun kò ha ti yàn awọn talakà aiye yi ṣe ọlọrọ̀ ni igbagbọ́, ati ajogun ijọba na, ti o ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ?**

**Ifihàn 2:9**
**Emi mọ̀ iṣẹ rẹ, ati iponju, ati aini rẹ (ṣugbọn ọlọ́rọ̀ ni ọ). . .**

Ewu wa ninu ọrọ aiye

**I Timoteu 6:17-19**
**Kìlọ fun awọn ti o lọrọ̀ li aiye isisiyi, ki nwọn máṣe gberaga, bẹni ki nwọn máṣe gbẹkẹle ọrọ̀ aidaniloju, bikoṣe le Ọlọrun alãye, ti nfi ohun gbogbo fun wa lọpọlọpọ lati lo; Ki nwọn ki o mã ṣõre, ki nwọn ki o mã pọ̀ ni iṣẹ rere, ki nwọn mura lati pin funni, ki nwọn ki o ni ẹmi ibakẹdun; Ki nwọn ki o mã tò iṣura ipilẹ rere jọ fun ara wọn dè igba ti mbọ̀, ki nwọn ki o le di ìye tõtọ mu.**

**Iṣe 20:32**

Nję nisisiyi, ará, mo fi nyin le Ọlọrun lọwọ, ati ọ̀rọ ore-ọfẹ rẹ̀, ti o le gbe nyin duro, ti o si le fun nyin ni ini lãrin gbogbo awọn ti a sọ di mimọ́.

**Filippi 3:21**

Ẹniti yio sọ ara irẹlẹ wa di ọ̀tun ki o le bá ara ogo rẹ̀ mu, gẹgẹ bi iṣẹ-agbara nipasẹ eyiti on le fi tẹ ori ohun gbogbo ba fun ara rẹ̀.

**Kolosse 1:12, 13**

Ki a mã dupẹ lọwọ Baba, eniti o mu wa yẹ lati jẹ alabapin ninu ogún awọn enia mimọ́ ninu imọlẹ: Ẹniti o ti gbà wa kuro lọwọ agbara ọ̀kunkun, ti o si ṣi wa nipo sinu ijọba ayanfẹ Ọmọ rẹ̀.

**Kolosse 3:4**

Nigbati Kristi, ẹniti iṣe ìye wa yio farahàn, nigbana li ẹnyin pẹlu o farahàn pẹlu rẹ̀ ninu ogo.

**Efesu 3:6 ati 8**

Pe, awọn ti ki iṣe Ju jẹ alabajogun ati ẹya-ara kanna. . . Fun emi ti o kere ju ẹniti o kere julọ ninu gbogbo awọn enia mimọ́, li a fi ore-ọfẹ yi fun, lati wasu awamáridi ọrọ̀ Kristi fun awọn Keferi.

### Sekariah 9:9

Yọ gidigidi, iwọ ọmọbirin Sioni; ho, iwọ ọmọbirin Jerusalemu: kiyesi i, Ọba rẹ mbọ̀wá sọdọ rẹ: ododo li on, o si ni igbalà. . .

### Filippi 4:4

Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo: mo si tún wi, Ẹ mã yọ̀.

### Orin 32:11

Ki inu nyin ki o dùn niti Oluwa, ẹ si ma yọ̀, ẹnyin olododo; Ẹ si ma kọrin fun ayọ̀, gbogbo ẹnyin ti aiya nyin duro ṣinṣin.

### II Korinti 4:17

Nitori ipọnju wa ti o fẹrẹ, ti iṣe fun iṣẹju kan, o nṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa.

### Orin Dafidi 40:16

Ki gbogbo awọn ti nwá ọ, ki o ma yọ̀, ki inu wọn ki o si ma dùn sipa tirẹ: Ki gbogbo awọn ti o si fẹ igbala rẹ ki o ma wi nigbagbogbo pe, Gbigbega li Oluwa.

### Luku 10:20

Ṣugbọn ki ẹ máṣe yọ̀ si eyi, pe, awọn ẹmi nforibalẹ fun nyin; ṣugbọn ẹ kuku yọ̀, pe, a kọwe orukọ nyin li ọrun.

### Orin Dafidi 5:11

Nigbana ni gbogbo awọn ti ngbẹkẹle ọ yio yọ̀; Lai nwọn o ma ho fun ayọ̀, nitoriti iwọ dabobo wọn: Ati awọn ti o fẹ orukọ rẹ pẹlu yio ma yọ̀ ninu rẹ.

**Owe 8:36**

Ṣugbọn ẹniti o ṣẹ̀ mi, o ṣe ọkàn ara rẹ̀ nikà: Gbogbo awọn ti o korira mi, nwọn fẹ ikú.

**Heberu 12:25**

Kiyesi i, ki ẹ máṣe kọ̀ ẹniti nkilọ. Nitori bi awọn wọnni kò ba bọ́ nigbati nwọn kọ̀ ẹniti nkilọ li aiye, melomelo li awa kì yio bọ́ awa ti o pẹhinda si ẹniti nkilọ lati ọrun wá.

**Luku 13:24, 25**

Ẹ làkaka lati wọ̀ oju-ọ̀na koto: nitori mo wi fun nyin, enia pipọ ni yio wá ọ̀na ati wọ̀ ọ, nwọn kì yio si le wọle. Nigbati bãle ile ba dide lẹkan fũ, ti o ba si ti sé ilẹkun, ẹnyin o si bẹ̀rẹ si iduro lode, ti ẹ o ma kànkun, wipe, Oluwa, Oluwa, ṣí i fun wa; on o si dahùn wi fun nyin pe, Emi kò mọ̀ nyin nibiti ẹnyin gbé ti wá.

Aanu ti a kọ le pada di ibinu

**II Tessalonika 2:10-12**

Ati pẹlu itanjẹ aiṣododo gbogbo fun awọn ti nṣegbé; nitoriti nwọn kò gbà ifẹ otitọ ti a ba fi gbà wọn là. Ati nitori eyi, Ọlọrun rán ohun ti nṣiṣẹ iṣina si wọn, ki nwọn ki o le gbà eke gbọ́: Ki a le ṣe idajọ gbogbo awọn ti kò gbà otitọ gbọ́, ṣugbọn ti nwọn ni inu didùn ninu aiṣododo.

Kun fun ẹsẹ, ẹni egbe

**Johannu 3:18**

**Ẹniti o ba gbà a gbọ́, a ko ni da a lẹjọ; ṣugbọn a ti da ẹniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bíbi kanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ́.**

**Heberu 10:26, 27**

**Nitori bi awa ba mõmọ̀ dẹṣẹ lẹhin igbati awa ba ti gbà ìmọ otitọ kò tun si ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ mọ́. Bikọṣe ireti idajọ ti o ba ni lẹrù, ati ti ibinu ti o muná. . .**

**Gbogbo wa si dabi ohun aimọ́, gbogbo ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin; gbogbo wa si rẹ̀ bi ewe; aiṣedede wa si mu wa kuro bi afẹfẹ. —Isaiah 64:6**

A Dalẹjọ pẹlu Ọrọ

**Johannu 12:48**

**Ẹniti o ba kọ̀ mi, ti kò si gbà ọ̀rọ mi, o ni ẹnikan ti nṣe idajọ rẹ̀: ọ̀rọ ti mo ti sọ, on na ni yio ṣe idajọ rẹ̀ ni igbẹhin ọjọ.**

A Fẹẹ a si waa kiri

**I Johannu 4:9**

**Nipa eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmọ bíbi rẹ̀ nikanṣoṣo si aiye, ki awa ki o le yè nipasẹ rẹ̀.**

**Ifihàn 22:17**

**Ati Ẹmí ati iyawo wipe, Mã bọ̀. Ati ẹniti o ngbọ́ ki o wipe, Mã bọ̀. Ati ẹniti ongbẹ ngbẹ ki o wá. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ.**

O jẹ isiwere lati lo aiyeraiye ninu ijiya pẹlu esu ni Ọrun Apaadi nigbati iwọ iba wa ninu ayọ ti a ko le fi ẹnu sọ ninu Kristi ti iwọ yio si maa se alabapin itẹ lori gbogbo aiye titi lae!

**Luku 11:39, 40**

**Oluwa si wi fun u pe, Ẹnyin Farisi a ma fọ̀ ode ago ati awo-pọkọ́; ṣugbọn inu nyin kún fun irẹjẹ iwa-buburu. Ẹnyin alaimo-ye, ẹniti o ṣe eyi ti mbẹ lode, on kọ́ ha ṣe eyi ti mbẹ ninu pẹlu?**

**Matteu 7:26, 27**

**Ẹnikẹni ti o ba si gbọ́ ọ̀rọ temi wọnyi, ti kò si ṣe wọn, on li emi o fi wé aṣiwere enia kan ti o kọ́ ile rẹ̀ si ori iyanrin: Òjo si rọ̀, ikún omi si de, afẹfẹ si fẹ́, nwọn si bìlu ile na, o si wó; iwó rẹ̀ si pọ̀ jọjọ.**

**Orin Dafidi 53:1**

**AṢIWERE wi li ọkàn rẹ̀ pe, Ọlọrun kò si . . .**

**Isaiah 5:14**

**Nitorina ipò-okú ti fun ara rẹ̀ li àye, o si là ẹnu rẹ̀ li aini ìwọn: ati ogo wọn, ati ọ̀pọlọpọ wọn, ati ọṣọ́ wọn, ati awọn ẹniti nyọ̀, yio sọkalẹ sinu rẹ̀.**

**Jeremiah 17:11**

**Bi aparo ti isaba lori ẹyin ti kò yin, bẹ̃ gẹgẹ ni ẹniti o kó ọrọ̀ jọ, ṣugbọn kì iṣe ni ododo; yio fi i silẹ lagbedemeji ọjọ rẹ̀, ati ni opin rẹ̀ yio jẹ aṣiwere.**

Ti gbogbo ẹniti ko ba gba Ọba Ogo naa yio lọ

**Heberu 6:8**

**Ṣugbọn eyiti o nhù ẹgún ati oṣuṣu, a kọ̀ ọ, kò si jìna si egún; opin eyiti yio jẹ fun ijona.**

**Matteu 13:41, 42**

**Ọmọ-enia yio rán awọn angẹli rẹ̀, nwọn o si kó gbogbo ohun ti o mu-ni-kọsẹ̀ ni ijọba rẹ̀ kuro, ati awọn ti o ndẹṣẹ. Yio si sọ wọn sinu iná ileru: nibẹ li ẹkún on ipahinkeke yio gbe wá.**

**Ifihán 14:11**

**Efin oró wọn si nlọ soke titi lailai, nwọn kò si ni isimi li ọsán ati li oru, awọn ti nforibalẹ fun ẹranko na ati fun aworan rẹ̀, ati ẹnikẹni ti o ba si gbà àmi orukọ rẹ̀.**

**Filippi 3:18, 19**

**. . .pe, ọtá agbelebu Kristi ni nwọn: Igbẹhin ẹniti iṣe iparun. . .**

Ọlọrun mura tan lati se isẹ iyanu lati ma jẹ ki a lọ si ọrun apaadi, debi pe O doju kọ ọrun apaadi naa fun wa, O sẹgun iku aiyeraiye, O jinde ki a ba le ri isẹgun yi ninu Rẹ ki a si ye. Omiran ni lati yi ẹlẹsẹ pada kuro ninu isọtẹ si ọkan titun ti ifẹ ninu Kristi.

# ỌBA AWỌN ỌBA YIO FI SATANI SINU ẸWỌN NIGBATI O BA WU U

**Ifihàn 20:1-3**

**MO si ri angẹli kan nti ọrun sọkalẹ wá, ti on ti kọkọrọ ọgbun nì, ati ẹwọn nla kan li ọwọ rẹ. O si di ikõko na mu, ejò atijọ nì, ti iṣe Èṣu, ati Satani, o si dè e li ẹgbẹrun ọdún, O si gbé e sọ sinu ọgbun na, o si ti i, o si fi èdidi di i lori rẹ, ki o má bã tan awọn orilẹ-ède jẹ mọ titi ẹgbẹrun ọdùn na yio fi pé: lẹhin eyi, a kò le ṣai tu u silẹ fun igba diẹ.**

**Ifihàn 20:7, 8 ati 10**

**Nigbati ẹgbẹrun ọdún na ba si pé, a o tú Satani silẹ kuro ninu tubu rẹ, yio si jade si jjade lọ lati mã tàn awọn orilẹ-ède ti mbẹ ni igun mẹrẹrin aiye jẹ, Gogu ati Magogu, lati gbá wọn jọ si ogun: awọn ti iye wọn dabi iyanrìn okun. . . . A si wọ Èṣu o tàn wọn jẹ lọ sinu adagun iná ati imi-ọjọ, nibiti ẹranko ati woli eke nì gbé wà, a o si mã dá wọn loro t'ọsan-t'oru lai ati lailai.**

Isẹgun patapata ati isẹgun aiyeraiye lori esu

**Heberu 2:14**

**Njẹ niwọn bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara on ẹjẹ, bẽ gẹgẹ li on pẹlu si ṣe alabapin ninu ọkanna; ki o le ti ipa ikú pa ẹniti o ni agbara ikú run, eyini ni Eṣu.**

**Matteu 6:24**

**Ko si ẹniti o le sìn oluwa meji: nitori yala yio korira ọkan, yio si fẹ ekeji; tabi yio faramọ ọkan, yio si yàn ekeji ni ipọsi. Ẹnyin ko le sìn Oluwa pẹlu mammoni.**

Iwọ yio ha maa tẹle satani lọ sinu ẹwọn, tabi Ọba awọn ọba si ori Itẹ Rẹ aiyeraiye?

**Ifihàn 21:8**

**Ṣugbọn awọn ojo, ati alaigbagbọ́, ati ẹni irira, ati apania, ati àgbèrè, ati oṣó, ati abọriṣa, ati awọn eke gbogbo, ni yio ní ipa tiwọn ninu adagun ti nfi iná ati imi-ọjọ jò: eyi ti iṣe ikú keji.**

**Iṣe 26:18**

**Lati là wọn li oju, ki nwọn ki o le yipada kuro ninu òkunkun si imọlẹ, ati kuro lọwọ agbara Satani si Ọlọrun, ki nwọn ki o le gbà idariji ẹ̀ṣẹ, ati ogún pẹlu awọn ti a sọ di mimọ́ nipa igbagbọ ninu mi.**

**Johannu 8:34-36**

**Jesu da wọn lohun pe, Lõtọ, lotọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba ndẹṣẹ, on li ẹrú ẹ̀ṣẹ. Ẹrú kì si igbé ile titilai: ọmọ ni igbe ile titilai. Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di omnira, ẹ ó di omnira nitõtọ.**

**Johannu 4:10, 14**

Jesu dahùn, o si wi fun u pe, Ibaṣepe iwọ mọ èbun Ọlọrun, ati èniti o wi fun ọ pe, Fun mi mu, iwọ iba si ti bère lọwọ rẹ̀, on iba ti fi omi íye fun ọ. . . . Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mu ninu omi ti emi o fifun u, orùngbẹ kì yio gbẹ ẹ mọ́ lai; ṣugbọn omi ti emi o fifun u yio di kanga omi ninu rẹ̀, ti yio ma sun si ìye ainipẹkun.

**Ifihàn 22:1-3**

O SI fi odò omi ìye kan han mi, ti o mọ́ bi kristali, ti nti ibi itẹ̀ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan jade wá. Li arin igboro rẹ̀, ati niha ikini keji odò na, ni igi iye gbé wà, ti ima so onirũru eso mejila, a si mã so eso rẹ̀ li oṣoṣù: ewé igi na si ni fún mimú awọn orilẹ-ède larada Ègún kì yio si si mọ́: itẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan ni yio si ma wà nibẹ̀; awọn iranṣẹ rẹ̀ yio si ma sìn i.

**Johannu 7:37**

Lọjọ ikẹhìn, ti iṣe ọjọ nla ajọ, Jesu duro, o si kigbe, wipe, Bi orùngbẹ ba ngbẹ ẹnikẹni, ki o tọ mi wá, ki o si mu.

**Ifihàn 7:17**

Nitori Ọdọ-Agutan ti mbẹ li arin itẹ́ na ni yio mã ṣe oluṣọagutan wọn, Ti yio si mã ṣe amọna wọn si ibi orisun omi iyè: Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn.

**Matteu 6:33**
Ṣugbọn ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ̀; gbogbo nkan wọnyi li a o si fi kún u fun nyin.

**Deuteronomi 4:29**
Ṣugbọn bi iwọ ba wá OLUWA Ọlọrun rẹ lati ibẹ̀ lọ, iwọ o ri i, bi iwọ ba fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ wá a.

**Hosea 10:12**
Ẹ funrugbin fun ara nyin li ododo, ẹ ká li ãnu: ẹ tú ilẹ nyin ti a kò ro: nitori o to akokò lati wá Oluwa, titi yio fi de, ti yio si fi rọ̀jo ododo si nyin.

**Owe 8:17**
Mo fẹ awọn ti o fẹ mi; Awọn ti o si wá mi ni kutukutu yio ri mi.

**Luku 11:9**
Emi si wi fun nyin, Ẹ bère, a o si fifun nyin; ẹ wá kiri, ẹnyin o si ri; ẹ kànkun, a o si ṣi i silẹ fun nyin.

**Isaiah 55:6**
Ẹ wá Oluwa nigbati ẹ le ri i, ẹ pè e, nigbati o wà nitosí.

**Orin 86:12**
Emi o yìn o, Oluwa Ọlọrun mi, tinutinu mi gbogbo: Emi o si ma fi ogo fun orukọ rẹ titi lai.

**Ifihàn 19:6-9**

Mo si gbọ́ bi ẹnipe ohùn ọ̀pọlọ̀pọ enia, ati bi iró omi pupọ̀, ati bi iró ãrá nlanla, nwipe, Halleuiah: nitori Oluwa Ọlọrun wa, Olodumare, njọba. Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: Nitoripe igbeyawo Ọdọ-Agutan de, Aya rẹ̀ si ti mura tan. On ni a si fifun pe ki o wọ aṣọ ọgbọ wíwẹ ti o funfun gbõ: Nitoripe aṣọ ọgbọ wíwẹ nì ni iṣe ododo awọn enia mimọ́. O si wi fun pe, Kọwe rẹ̀ Ibukún ni fun awọn ti a pè si àse-alẹ igbeyawo Ọdọ-Agutan. O si wi fun mi pe, Wọnyi ni ọ̀rọ otitọ Ọlọrun.

**Ifihàn 21:9-11 ati 22-24**

. . .Wá nihin, emi o fi iyawo, aya Ọdọ-Agutan, hàn ọ. O si mu mi lọ ninu Ẹmí si òke nla kan ti o si ga, o si fi ilu nì hàn mi, Jerusalemu mimọ́, ti nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun wá, Ti o ni ogo Ọlọrun. . .Emi kò si ri tẹmpili ninu rẹ̀: nitoripe Oluwa Ọlọrun Olodumare ni tẹmpili rẹ̀, ati Ọdọ-Agutan. Ilu na kò si wá õrùn, tabi oṣupa, lati mã tan imọlẹ si i: nitoripe ogo Ọlọrun li o ntàn imọlẹ si i, Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀. Awọn orilẹ-ède yio si mã rìn nipa imọlẹ rẹ̀. . .

Tẹriba fun U

**. . .ṣugbọn ẹ jọwọ ara nyin lọwọ fun Ọlọrun, bi alãye kuro ninu okú. . . —Romu 6:13**

Fẹran Ọkọ Iyawo

**Ki ore-ọfẹ wà pẹlu gbogbo awọn ti o fẹ Oluwa wa Jesu Kristi li aiṣẹtan. —Efesu 6:24**

Ọkan pẹlu Rẹ

**Nitoripe awa li ẹya-ara rẹ, ati ti ẹran-ara rẹ, ati ti egungun ara rẹ. —Efesu 5:30**

Kun fun agbara ọrun

**Eyiti a kò fi jẹ gẹgẹ bi ofin ilana nipa ti ara, bikoṣe nipa agbara ti ìye ailopin. —Heberu 7:16**

Kun fun ifẹ ọrun

**Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba npa ofin rẹ mọ́, lara rẹ li a gbé mu ifẹ Ọlọrun pé nitõto. . . —I Johannu 2:5**

Alailabawọn

**Iwọ li ẹwà gbogbo, olufẹ mi; Kò si abawọ́n lara re! —Orin Solomoni 4:7**

**Nitorina, olufẹ, bi ẹnyin ti nreti irú nkan wọnyi, ẹ mura giri, ki a le bá nyin li alafia, li ailabawọn, ati li ailàbuku li oju rẹ. —II Peteru 3:14**

Yio ni oore-ọfẹ kikun

**. . .eyiti a nmu bọ̀ fun nyin wá ni igba ifarahàn Jesu Kristi. —I Peteru 1:13**

**Ifihàn 18:21**
Angẹli alagbara kan si gbé okuta kan soke, o dabi ọlọ nla, o si jù u sinu okun, wipe, Bayi li a o fi agbara nla bì Babiloni ilu nla nì wó, A ki yio si ri i mọ lai.

**II Tessalonika 2:8**
Nigbana li a ó si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi ẽmi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwa rẹ̀ sọ di asan.

**Ifihàn 17:14**
Awọn wọnyi ni yio si mã ba Ọdọ-Agutan jagun, Ọdọ-Agutan na yio si ṣẹgun wọn: nitori on ni Oluwa awọn oluwa, ati Ọba awọn ọba: awọn ti o si wà pẹlu rẹ̀, ti a pè, ti a yàn, ti nwọn si jẹ olõtọ yio si ṣẹgun pẹlu.

**Sekariah 14:12**
Eyi ni yio si jẹ àrun ti Oluwa yio fi kọlu gbogbo awọn enia ti o ti ba Jerusalemu ja; ẹran-ara wọn, yio rù nigbati nwọn duro li ẹṣẹ̀ wọn, oju wọn yio si rà ni ihò wọn, ahọn wọn yio si sokì li ẹnu wọn.

**I Korinti 15:24**
Nigbana ni opin yio de, nigbati o ba ti fi ijọba fun Ọlọrun ani Baba; nigbati o ba ti mu gbogbo aṣẹ ati gbogbo ọla ati agbara kuro.

# ẸGBẸRUN ỌDUN IYAWO OLOYINMỌMỌ LORI 47 ILẸ AIYE

**Matteu 6:10**
Ki ijọba rẹ de; Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, Bi ti ọrun, bẽni li aiye.

**Matteu 5:5**
Alabukún-fun li awọn ọlọkàn-tutù: nitori nwọn o jogún aiye.

**Ifihàn 11:15**
. . .Ijọba aiye di ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ̀; on o si jọba lai ati lailai.

**Ifihàn 5:9, 10**
. . .Iwọ li o yẹ lati gbà iwe na, ati lati ṣí èdidi rẹ̀: Nitoriti a ti pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ rẹ ṣe ìrapada enia si Ọlọrun Lati inu ẹyà gbogbo, ati ède gbogbo, ati enia gbogbo, ati orilẹ-ède gbogbo wá: Iwọ si ti ṣe wọn li ọba ati alufa si Ọlọrun wa: Nwòn njọba lori ilẹ aiye.

**Ifihàn 20:4**
Mo si ri awọn ìtẹ́, nwọn si joko lori wọn, a si fi idajọ fun wọn: mo si ri ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹrí Jesu, ati nitori ọ̀rọ Ọlọrun. . . .

**Ifihàn 20:6**
Olubukun ati mimọ́ ni ẹniti o ni ipa ninu ajinde ekini na: lori awọn wọnyi ikú ekeji kò li agbara, ṣugbọn nwọn o jẹ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, nwọn o si mã jọba pẹlu rẹ̀ li ẹgbẹ̀run ọdún.

Ọlọrun ati emi yio maa gbe lailopin, Ayọ nla!

**Orin 145:1**

**Emi o gbé ọ ga, Ọlọrun mi, ọba mi; Emi o si ma fi ibukún fun orukọ rẹ lai ati lailai.**

**Johannu 17:24**

**Baba, emi fẹ ki awọn ti iwọ fifun mi, ki o wà lọdọ mi, nibiti emi gbé wà; ki nwọn le mã wò ogo mi, ti iwọ ti fi fifun mi. . .**

**Ifihàn 21:3, 4**

**. . .Kiyesi i, agọ́ Ọlọrun wà pẹlu awọn enia, on ó si mã ba wọn gbé, nwọn o si mã jẹ enia rẹ̀, ati Ọlọrun tikararẹ̀ yio wà pẹlu wọn, yio si mã jẹ Ọlọrun wọn. Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn; kì yio si si ikú mọ́, tabi ọfọ, tabi ẹkún, bẽni ki yio si irora mọ́: nitoripe ohun atijọ ti kọja lọ.**

**I Tessalonika 4:16, 17**

**. . .awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: Nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa ó si ma wà titi lai lọdọ Oluwa.**

**Ifihàn 22:5**

**Oru kì yio si si mọ́; nwọn kò si wá imọlẹ fitila, tabi imọlẹ õrùn; nitoripe Oluwa Ọlọrun ni yio tan imọlẹ fun wọn: nwọn o si mã jọba lai ati lailai.**

## KRISTI WIPE:

**"Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ rẹ." — Ifihàn 3:21**

**Ninu Kristi a da mi fun nkan nla!**
**Ohun ti o peye npe mi, mo si nilati lọ,**
**O ya si isẹgun!**

**O, Ifẹ nla ti Olugbala ọwọn ti fi han,**
**Lati ku iku itiju lori igi,**
**Ti O fi ọpa asẹ ati itẹ Rẹ daradara silẹ,**
**Lati gba ẹlẹsẹ bi emi la. — I. N. McHose**

**Yin Oluwa, O jẹ mimọ ati olootọ;**
**Yin Oluwa, O fẹ mi, ẹni erupẹ;**
**Yin Oluwa, MO NILATI SIN I!**
**Yin Oluwa! Yin Oluwa! YIN OLUWA!**

Scripture text reprinted from the Bible in Yoruba, 1969 Corrected Edition, by permission of the United Bible Societies Africa Regional Centre, Nairobi, Kenya.

---

Published in numerous languages as God supplies funds in answer to prayer. If you would like more copies for prayerful distribution, write in English. Specify which language(s) you need and how many booklets.

**World Missionary Press, PO Box 120, New Paris, IN 46553-0120 USA**

Read booklets online or by App
www.wmp-readonline.org

www.wmpress.org 5-17 533 Yoruba WAI